# Ko Si Ẹniti Ko Mọ Ọgbọn K'a Fi Ẹran Sẹnu Ki A Wa Ti

Mo ki Olotu, mo si juba awọn agbalagba ilẹ Oduduwa ọrọ mi oni dori ọgbọn ẹtan ti ẹgbẹ ti wọn npe ni NNDP fẹ fi sọ gbogbo Yoruba di ẹru awọn Gambar owe awọn baba wa lo sọ wipe "Ẹniti antanjẹ kogbọn, ẹnito ntan ni jẹ nigbọn juni lọ.

## Lati Ọwọ Kekere Awo. Awẹ

Mofẹ ki oye gbogbo ọmọ Yoruba wipe ẹgbẹ Dẹmọ ko wa fun iṣọkan Yoruba bi wọn tiṣe npariwo kiri, bi koṣe wipe ẹtan lati di awa Yoruba mọnu lawani awọn Hausa.

Idi na ni pe ọgbọn ti Akintọla nda ko ju wipe, o ti mọ wipe bi on ko ba da ẹgbẹ kan silẹ ki on lọdi rẹ pọ mọ awọn Hausa, ni gba kugba ni wọn le gbọn on nigbẹ, nitoripe wiwa towa ni olori Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun kiṣe ifẹ inu awọn ọmọ Yoruba bikoṣe pẹlu alubarika awọn Hausa.

O si mọ daju wipe bi on ko ba da ẹgbẹ kan silẹ ki on lọdi rẹ pọ mọ awọn Hausa nwọn le fi agbara tu ile igbimọ Ijọba Ipinle Iwọ Orun ka, ki nwọn jẹki ibo didi o waiye

Osi dami loju wipe bi ibo didi ba waiye ni Ipinlẹ Iwọ Orun Bakodaya ni Akintọla ati awọn ẹgbẹ rẹ yio ko.

Bo ba si jẹ wipe ohun ti mo sọ yi ko ribẹ ki ẹgbẹ Dẹmọ tule Igbimọ Ijọba Iwọ Orun ka, ki nwọn jẹki awọn ọmọ onile dibo yan Ijọba ti wọn fẹ. O dami loju gbangba wipe ẹgbẹ Afẹnifẹre ni yio gba ijọba wọn pada laisi aniani.

### ETO IKANIA

Ki ẹjẹki ati ibi isana kiye si ogun, nigbati ọrọ abayọri ikaniyan delẹ ti Olotu Ijọba Ila Orun (Opara) nkigbe pe abayori enia kika ko dara rara, eṣe ti oloye Akintọla fi tete kede wipe on gba

Tulasi oni lati gba nitoripe bi o ba le sọ ade wipe on ko gba, koto to ijọ kan si ojọ keji awọn Gambari yio sa ni ake wọn lori, o ti da loju pe bẹni,

Bi ohun kohun ba ṣẹlẹ ni orilẹ-ede Naijiria toba jẹ wipe bi Akintọla ba fọwọ si yio pa Ipinlẹ Iwọ Orun lara yio si gbe ilu awọn Hausa ga, Akintọla koni ba ẹnikẹni sọ ti yio fi fọwọ si ru nkan bẹ, nitori ki ipo tirẹ ma ba bọ ni ọwọ rẹ.

Apẹrẹ iru rẹ ni ohun ti o ṣe nipa ti abajade enia kika. Bi o ba kọ lati fọwọ siru iwe bẹ fun awọn Hausa dajudaju oti mọ wipe awọn ni lati sa on ni ake lori ni.

Nitori idi eyi, emi fẹki o ye gbogbo wa daju wipe ẸGBẸ DẸMỌ ki ṣe fun isọkan Yoruba bi ko ṣe fun isọkan ati ilọsiwaju Oloye Akintọla ati awọn ẹmẹwa rẹ Ki ẹfi oju inu wo alaye yi, ki esi fi ọgbọn Yoruba gbe daradara, ki ẹ tun fi ro ara nyin wo pẹlu.

Emi ko lodi si wipe ki Ijọba iwo Orun a ni ajọṣẹ pọ pẹlu awọn Hausa, ṣugbọn o ni lati jẹ ijọba ti adibo fun, ti ọkan wọn yio balẹ pẹlu ijọba wọn, ti nwọn yio si le lagbara lati le kọ ohun ti nwọn ba ri pe ko ni ran orilẹ-ede Yoruba lọwọ.

### OKELE ẸBA

Ki ṣe ijọba na fun aiya fun to jẹ wipe bi Sadauna ba ti paṣẹ kan, o dara ni, ko dara ni ao gbọdọ gba, nitori okele ẹba ti wọn, kini okele ẹba ti wọn ṣe le tan iṣẹ gbogbo awọn agba ati awọn ti kori iṣẹ ṣe ni ipinlẹ Iwọ Yoruba Ara mi, ẹ fi ọgbọn ori gbe alaye mi yi ko ro jinlẹ.

Oloye Akintọla paapa ko le sọ wipe ojuborọ ni on fi da ẹgbẹ DẸMỌ pọ mọ ẹgbẹ Olomi, nitoripe o ri wipe bi on ko ba ṣebẹ omi yio tan lẹhin ẹja. ọwọ yio si tẹ ẹja lo jẹ ko ṣe eyi, ko ni nkankan lati ṣe pẹlu iṣọkan Yoruba.

Owe Yoruba sọ pe "Apọ ju ipọnju ni muni kundun ponmọ, ko si omi tontoro to wa lara awọ.

Bi ẹgbẹ Dẹmọ ba sọ fun aiye wipe awọn wa fun iṣọkan ọmọ Yoruba, kini ipin awọn bi ogun ọmọ Yoruba to wa ninu ọgba ẹwọn bi AWOLỌWỌ ati awọn yoku yio jẹ? A bi iṣọkan ti wọn ko wolo, nitoripe nwọn ti wa lẹwọn.

Kẹ maṣe gbagbe Maku marun kiṣe titi lai, ẹgbẹrun ọdun ṣi nbọ wa ku ola, oju a tun ara wọn ri.

Iṣọkan ki iṣọkan ti a ba nfẹ ni ilẹ Yoruba ti AWOLỌWỌ ko ba lọwọ ni, u rẹ ki ṣe iṣọkan, nitoripe nigbati Aja fi nṣọṣẹ ninu ile, nin igbẹ ni ọbọ wa.

Ki ẹ jẹki ori nyin fapo, ọmọ Yoruba atata, ki ẹ si ronu nipa Dẹmọ wipe ẹgbẹ ologongomu niwọn jẹ, apo ara gbogbo wọn niwọn si ndu kiṣe iṣọkan Yoruba. Ao tun kesi ara wa laipẹ ọjọ.

Mo dupẹ lọwọ Olotu. Yio dara fun gbogbo wa o (Aṣẹ).

# Ala ati Itumọ

J. O. Kọlade Idanre:— Ṣọra nipa irin ajo loju omi n ọsẹ yi ki o ma ba ku iku omi.

J. F. Folaranmi Ibadan — Iwọ yio gbọ iro rere ti yio ṣe ọ ni anfani.

T. B Akintan Eko — Aisan airotẹlẹ yio talu ọ ti o kọ ba ṣọra Kun fun adura

Samson Otẹ bẹiyẹ Ibadan — Ch ohkohun ti o ba dawọ le laseko yi rere ni yio jasi.

Babalọla Aisu Badagry — Ire owo, ọmọ ati alafia ni itumọ ala rẹ.

Joseph Adegoke Ẹpe — Maṣe fi i u r han awọn ti o npe ni ọrẹ r laseko yi, ki nwọn ma ba fi ọb ẹhin jẹ ni iṣu.

Fatayi Phillips Shagamu — Ṣọra nipa iyan jija, ki o ma ba gbe ẹ de ile ẹjọ lairotẹlẹ

Fi ala rẹ ranṣẹ si:—
Josefu Alala,
1, Isiba Street,
c/o Postal Agent,
Itirẹ
Suru Lere
Via Yaba.

# IWE ITUMỌ ALA

Josefu Alala ti ẹ ti nka ninu iwe Irohin Yoruba ti jade ni odindi fun tita nisisiyi.

### OHUN TI O WA NINU IWE NA

1. Egbogi Ajẹbidan agbabiẹtu.
2. Odu Ifa mẹrindinlogun lati ma a fi yẹ itumọ ala rẹ wo
3. Ẹnikẹni ti o ba ra iwe yi ni anfani lati bere ala rẹ nigba gbogbo lọfẹ lọwọ Josefu Alala.
4. Koiti si ikeji rẹ ninu iwe itumọ ala ti o ti njade ri nitoripe JOSẸFU ALALA ni o ṣe e

Tete ra tirẹ loni ki o to tan.

AKIYESI

A tun nfẹ asoju ti yio ma ba wa ta iwe na, owo pọọku ni ao ta fun wọn ki nwọn ba ri ere gọbọi jẹ bi o ba fẹ se asoju wa kọwe fun iwe adehun.

Iye owo 5/- £2

**J. O. Shoyinka**
N/ Shittu Street
Ibadan

tabi

1, Isiba Street Odo Ẹran
c/o Postal Agent
Itirẹ.
Via Suru—Lere,
Yaba

# Ko Si Ẹniti Ko Mọ Ọgbọn K'a Fi Ẹran Sẹnu Ki A Wa Ti

Mo ki Olotu, mo si juba awọn agbalagba ilẹ Oduduwa ọrọ mi oni dori ọgbọn ẹtan ti ẹgbẹ ti wọn npe ni NNDP fẹ fi sọ gbogbo Yoruba di ẹru awọn Gambar owe awọn baba wa lo sọ wipe "Ẹniti antanjẹ kogbọn, ẹnito ntan ni jẹ nigbọn juni lọ.

## Lati Ọwọ Kekere Awo. Awẹ

Mo fẹ ki oye gbogbo ọmọ Yoruba wipe ẹgbẹ Dẹmọ ko wa fun iṣọkan Yoruba bi wọn tiṣe np riwo kiri, bi koṣe wipe ẹtan lati di awa Yoruba mọnu lawani awọn Hausa.

Idi na ni pe ọgbọn ti Akintọla nda ko ju wipe, o ti mọ wipe bi on ko ba da ẹgbẹ kan silẹ ki on lọdi rẹ pọ mọ awọn Hausa, ni gba kugba ni wọn le gbọn on nigbẹ, nitoripe wiwa towa ni olori Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun kiṣe ifẹ inu awọn ọmọ Yoruba bikoṣe pẹlu aiubarika awọn Hausa.

O si mọ daju wipe bi on ko ba da ẹgbẹ kan silẹ ki on lọdi rẹ pọ mọ awọn Hausa nwọn le fi agbara tu ile igbimọ Ijọba Ipinle Iwọ Orun ka, ki nwọn jẹki ibo didi o waiye

Osi dami loju wipe bi ibo didi ba waiye ni Ipinlẹ Iwọ Orun Bakodaya ni Akintọla ati awọn ẹgbẹ rẹ vio ko.

Bo ba si jẹ wipe ohun ti mo sọ yi ko rihẹ ki ẹgbẹ Dẹmọ tule Igbimọ Ijọba Iwọ Orun ka, ki nwọn jẹki awọn ọmọ onile dibo yan Ijọba ti wọn fẹ. O dami loju gbangba wipe ẹgbẹ Afẹnifẹre ni yio gba ijọba wọn pada laisi aniani.

ETO IKANIA

Ki ẹjẹki ati ibi isana kiye si ogun, nigbati ọrọ abayọri ikaniyan delẹ ti Olotu Ijọba Ila Orun (Opara) nkigbe pe abayori enia kika ko dara rara, eṣe ti oloye Akintọla fi tete kede wipe on gba.

Tulasi oni lati gba nitoripe bi o ba le sọ ,ade wipe on ko gba, koto to ijọ kan si ọjọ keji awọn Gambari yio sa ni ake wọn lori, o ti da loju pe bẹni.

Bi ohun kohun ba ṣẹlẹ ni orilẹ-ede Naijiria toba jẹ wipe bi Akintọla ba fọwọ si yio pa Ipinlẹ Iwọ Orun lara yio si gbe ilu awọn Hausa ga, Akintọ'a koniba ẹnikẹni sọ ti yio fi fọwọ si ru nkan bẹ, nitori ki ipo tirẹ ma ba bọ ni ọwọ rẹ.

Apẹrẹ iru rẹ ni ohun ti o ṣe nipa ti abajade enia kika. Bi o ba kọ lati fọwọ siru iwe bẹ fun awọn Hausa dajudaju oti ...ọ wipe nwọn ni lati sa on ni ake lori ni.

Nitori idi eyi, emi fẹki o ye gbogbo wa daju wipe ẸGBẸ DẸMỌ ki ṣe fun isọkan Yoruba bi ko ṣe fun isọkan ati ilọsiwaju Oloye Akintọla ati awọn ẹmẹwa rẹ Ki ẹfi oju inu wo alaye yi, ki esi fi ọgbọn Yoruba gbe daradara, ki ẹ tun fi ro ara nyin wo pẹlu.

Emi ko lodi si wipe ki Ijọba iwo Orun a ni ajọṣẹ pọ pẹlu awọn Hausa, ṣugbọn o ni lati jẹ ijọba ti adibo fun, ti ọkan wọn yio balẹ pẹlu ijọba wọn, ti nwọn yio si le lagbara lati le kọ ohun ti nwọn ba ri pe ko ni ran orilẹ-ede Yoruba lọwọ.

OKELE ẸBA

Ki ṣe ijọba na fun aiya fun to jẹ wipe bi Sadauna ba ti paṣẹ kan, o dara ni, ko dara ni ao gbọdọ gba, nitori okele ẹba ti wọn, kini okele ẹba ti wọn ṣe le tan iṣẹ gbogbo awọn agba ati awọn ti kori iṣẹ ṣe ni ipinlẹ Iwọ Yoruba Ara mi, ẹ fi ọgbọn ori gbe alaye mi yi ko ro jinlẹ.

Oloye Akintọla paapa ko le sọ wipe ojuborọ ni on fi da ẹgbẹ DẸMỌ pọ mọ ẹgbẹ Olomi, nitoripe o ri wipe bi on ko ba ṣebẹ omi yio tan lẹhin ẹja. ọwọ yio si tẹ ẹja lo jẹ ko ṣe eyi, ko ni nankan lati ṣe pẹlu iṣọkan Yoruba.

Owe Yoruba sọ pe "Apọju iponju ni muni kundun pọnmọ, ko si omi tontoro to wa lara awọ.

Bi ẹgbẹ Dẹmọ ba sọ fun aiye wipe awọn wa fun iṣọkan ọmọ Yoruba, kini ipin awọn bi ogun ọmọ Yoruba to wa ninu ọgba ẹwọn bi AWOLỌWỌ ati awọn yoku yio jẹ? A bi iṣọkan ti wọn ko wolo, nitoripe nwọn ti wa lẹwọn.

Kẹ maṣe gbagbe Maku marun kiṣe titi lai, ẹgbẹrun ọdun ṣi nbọ wa ku ola, oju a tun ara wọn ri.

Iṣọkan ki iṣọkan ti a ba nfẹ ni ilẹ Yoruba ti AWOLỌWỌ ko ba lọwọ ni, u rẹ ki ṣe iṣọkan, nitoripe nigbati Aja fi nṣọge ninu ile, nin igbẹ ni ọbọ wa.

Ki ẹ jẹki ori nyin fapo, ọmọ Yoruba atata, ki ẹ si ronu nipa Dẹmọ wipe ẹgbẹ alogongomu niwọn jẹ, apo ara gbogbo wọn niwọn si ndu kiṣe iṣọkan Yoruba. Ao tun kesi ara wa laipẹ ọjọ.

Mo dupẹ lọwọ Olotu. Yio dara fun gbogbo wa o (Aṣẹ).

# Ala ati Itumọ

J. O. Kọlade Idanre:— Ṣọra nipa irin ajo loju omi n ọsẹ yi ki o ma ba ku iku omi.

J. F. Folaranmi Ibadan — Iwọ yio gbọ iro rere ti yio ṣe ọ ni anfani.

T. B Akintan Eko — Aisan airotẹlẹ yio talu ọ ti o ko ba ṣora Kun fun adura

Samson Ọtẹ bẹiyẹ Ibadan — Ch ekohun ti o ba daw... le laseko y rere ni yio jasi.

Babalọla Aisu Badag y — Ire owo, ọmọ ati alafia ni itumọ ala rẹ.

Joseph Adegoke Ẹpe — Maṣe fi i u r han awọn ti o npe ni ọre r laseko yi, ki nwọn ma ba fi ọb ẹhin jẹ ni iṣu.

Fatayi Phillips Shagamu — Ṣọra nipa iyan jija, ki o ma ba gbe ẹ de ile ẹjọ lairotẹlẹ

Fi al rẹ ranṣẹ si:—
Josefu Alala,
1, Isiba Street,
c/o Postal Agent,
Itirẹ
Suru Lere
Via Yaba.


# IWE ITUMỌ ALA

Josefu Alala ti ẹ ti nka ninu iwe Irohin Yoruba ti jade ni odindi fun tita nisisiyi.

OHUN TI O WA NINU IWE NA

1. Egbogi Ajẹbidan agbabiẹtu.
2. Odu Ifa mẹrindinlogun lati ma a fi yẹ itumọ ala rẹ wo
3. Ẹnikẹni ti o ba ra iwe yi ni anfani lati bere ala rẹ nigba gbogbo lọfẹ lọwọ Josefu Alala.
4. Koiti si ikeji rẹ ninu iwe itumọ ala ti o ti njade ri nitoripe JOSẸFU ALALA ni o ṣe e

Tete ra tirẹ loni ki o to tan.

AKIYESI

A tun nfẹ asoju ti yio ma ba wa ta iwe na, owo pọọku ni ao ta fun wọn ki nwọn ba ri ere gọbọi ie bi o ba fẹ se asoju wa kọwe fun iwe adehun.

Iye owo 5/- £2

J. O. Shoyinka
N/ Shittu Street
Ibadan

tabi

1, Isiba Street Odo Ẹran
c/o Postal Agent
Itirẹ.
Via Suru—Lere,
Yaba

# Oluwa Maṣe Jẹki Esu Jẹwa lere

Lati Ọwọ HADJI Y. A. DISU Eko.

Lati igbati Alaiye ti da aiye, lati igba iwaṣe ni awọn Oloriṣa ati awọn Musulumi ati awọn ọmọlẹhin Jesu Kristi ti nfun awọn ọmọ enia ni imọran pe, ki a ma a huwa ọmọluwabi, ki ni iwa ire si ara wa ni gbogbo igba. Nwọn si fi nye wa yekeyeke pe ki a ma a ṣe akiyesi iṣẹ Olodumare, ao si ri i pe, iṣẹ ire ni o ma a nṣe fun wa ni gbogbo igba.

Nwọn ni a ma a fi tirẹ ṣe arikọgbọn. Ṣugbọn melo ninu awa ọmọ enia ni a gbọ ti a si gba ẹkọ oniyebiye yi ti o dara ti o si peye ju fadaka ati wura lọ? Jẹu aboosi, iwa tẹmbẹlẹkun, iwa onisọdi sọdi, iwa kẹnimani, iwa ẹgbotẹku wi-f'ẹiyẹ ati iwa aisododo, a ni iwa eṣu ti jọba si ẹgẹọrẹ ọmọ araiyẹ lọkan. Eyi ni o sọ aiye kodo. Eyi ni o mu ki aiye ti wa ri bi o ti ṣe wa loni, Baba ko gbọ t'ọmọ mọ, ọmọ ko si gbọ ti baba mọ. aiya ko gbọ t'ọkọ mọ. ọkọ ko si gbọ t'aya mọ. Dipo ki baba ṣe itoju ọmọ ati aya rẹ, a ma a lọ ṣe itoju ale ati ọmọ ale.

Dido ki aya gbọ t'ọkọ, ti ale ni yio ma a mu gbọ. Dipo ki Mọgaji ile ṣe awọn ọmọ ẹgbọn ati awọn ọmọ aburo rẹ lọkan, nṣe ni yio ma a fi ori ara wọn gba ara wọn. Ko si ni ifẹ ododo si wọn.

Ẹjọwọ, ẹnyin ọmọ enia, ẹ jẹki a ronupiwada, ki a ye'se eke, eke ni o npani. Ẹjẹki a jawọ kuro ninu eepo ẹpa ti ko ni ẹmọ ninu.

Ẹjẹki ama a huwa ire ni gbogbo igba si t'aja t'ẹran. Eye ba ara nyin jẹ mọ. Ẹ ye purọ ti o gajulọ mọ awọn Aburo ati awọn ọrẹ nyin mọ Ẹni ti o ba ọmọ lakeji rẹ jẹ, alamọri ara rẹ ni o nbajẹ.

Ẹma ṣe iraiti ni igba gbogbo pe, ijọba ọrun ku si dẹdẹ. Ẹni ti o ba ṣe iṣẹ re yio ri ire.

Ẹni ti oba siṣe iṣẹ buburu, yio ri ibi. T'ka t'oore, ọkan ko gbe. Melomelo ni ojo ti oti rọ ti ilẹ si ti fi mu.

Melo melo ni onişẹ ibi ti nwọn si ti ke igbe oro ki, Oluwa rere, a bẹ Ọ, fi gbogbo wa mọna o.

Maşe jẹki apa ọta ka wa Maşe jẹki eşu jẹ wa lere o. Amin.

# YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb. 20) Ọjọ pataki ni ọjọ Alaruba yio jẹ fun ọ, nipa owo ati iaaji, gbidanwo lati tẹle imọran ti nwọn ba fun ọ, iwọ o si ri okan iyanu ni alẹ maşe na inakuna.

PISCES Feb. 21-Marh 20) Ṣe pẹlẹpẹlẹ ki o maşe fi ohun ti o nfẹ şere, ma a ṣe ọyaya si enia, ni ọjọrọ ire aburadi kan yio yọ si ọ nitorina, ro eyiti iwọ yio şe.

ARIES (March 21-April 20) Ṣọra ki o maşe fi owo rẹ şe yẹyẹ lọ wo akẹşilẹ rẹ, ki o mọ eyiti oyẹ ki o şe, maşe şe işekuşe Iwe ti o si fẹ kọ, o yẹ kio mọ iru ọrọ ti iwọ yio sọ jade lenu.

TAURUS (April 21-May 20) Gbogbo işan ara rẹ ati ti awọn aladugbo nfẹ şe amọdi, şugbọn a ko ni fi ọ şe apẹrẹ maşe şe ẹabogi Awure bi o ba danwo, iwọ yio wa omi ti loju rẹ.

GEMINI (May 21 - June 21) Bi o ba pinnu lati şe jẹjẹ loni ire yio jẹ tirẹ, Iwọ yio si jare ninu ọrọ kan ti ẹ fẹ pari rẹ Maşe şeşekuşe ki o ma ba jẹ ika rẹ,

CANCER (June 22 - July 23) Ṣọ owo rẹ ni nina şugbọn lọ si ode, maşe rin irinajo Işẹ rẹ yio ma gberu Dupẹ lọwọ ori rẹ to pe, alẹ oni yio minringindin fun ọ şugbọn maşe ni inakuna,

LEO (July 24 - Aug 22) Fi gbogbo ọsan ọjọ oni şe itọju awọn ọrẹ ati ojulumọ rẹ. Dupẹ lọwọ ori rẹ to pe, maşe gbamọran ẹlomiran loni, fun ọjọ meje ni imọlẹ irawọ rẹ yio fi tan.

VIRGO (Aug 23 - Sept 23) Ilopọ iwọ pẹlu ẹlomiran ko ni sunwọn loni, kọ ẹbọn rẹ nijanu, ki o si ma sọ ọrọ ti iwọ yio sọ, ki o ma ba sọ ọrọ kan tan eyiyi si le sọ ọ di akuşẹ.

LIBRA (Sep.24 Oct 23) Sọra nipa idajọ eke, bi o ba si fẹ şe bi o ti to, yio dabi konge Tọju ẹmi ara rẹ, loba, ire ojiji kan yio kan ọ lara

SCORPIO (Oct24 Nov22) Şọra maşe jẹki ara dun ọ depo ti ija kan ti o ti wa nilẹ pari loni tọju alafia ara rẹ jẹki ẹlomiran pari rẹ fun ọ

SAGITTORIUS (Nov23-Dec22) Şe ore ti o ni gọmbo, Ara rẹ si nfẹ itoju gidigidi

CAPRICORN (Dec23-Jan21) Maşa gbagbe awọn olufẹ rẹ nigba ti aiye ba san ọ Şọrọ maşe lọ si ode loni

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki wọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan işẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi şişe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa di ọkun lọsan tabi loru tabi awọn işan ara rẹ gbogbo ki şe fun daradara ti Eemi (Breath) inn ko ba gunlẹ daradarawọn işẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo eyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun lọ si ded'aderin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ 'DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹ rẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igbadun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju Bere Egbogi na ni Şọbu:-

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Stree Lagos.

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹtadinlogun oşu karun (71/5/64) ni dede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Eko.

Ao si tun fi iyọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipape lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki e tete de o.

LATIFU BABALỌLA
Akọwe Agba

# Ọtẹlẹmuyẹ Nki Nyin o!

Ẹ ku owuro Olotu, se daada lẹ ji loni o, ara le tabi ko le? Mo ki awọn onkawe Irohin Imọlẹ pe, ara o le bi o. Mo ti pa ọrọ ana ti, imirao nimo tun mu sọ lowurọ yi. A ṣe ọrọ ti Alapara Ibadan nsọ, ko si irọ kankan nibẹ nipati ọrọ awọn Woli eke, ana ni mo to mọ.

Ẹnyin onkawe mi, ẹsọra gidigidi ki ẹ ma baa bọ si ikẹku awọn Woli Eke nitoripe awọn ti de jaburata si arin ilu paapajulọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Eyi ko le ya mi lẹnu nitoripe iwe mimọ papa sọ bayi pe Olufẹ, ẹ mase gba gbogbo ẹmi gbọ, ṣugbọn ẹ dan awọn ẹmi wo bi nwọn ba ṣe ti Ọlọrun nitori awọn Woli eke pupọ ti jade sinu aiye (Johanu kini ori 4 ẹsẹ 1) nitotọ nwọn ti jade sinu aiye, nṣe ni wọn nda luru kakiri ti nwọn si nfi orukọ Ọlọrun jẹun kakiri paapa lọdọ awọn obinrin alaimọkan.

Ṣugbọn iwe Mimọ tun fi nye awọn Woli eke bakanna pe. "Ẹniti nṣe alaisotọ ki o ma ṣe alaisotọ nṣo, ati ẹniti nṣe ẹlẹgbin, ki o ma a ṣe ẹlẹgbin nṣo, ati ẹniti nṣe olododo, ki o ma ṣe olododo nṣo, ati ẹniti nṣe mimọ ki o ma ṣe mimọ nṣo. Kiye si i emi mbọ ankan, ere ere mi si mbẹ pẹlu mi, lati san fun olukuluku gẹgẹbi iṣẹ rẹ yio ti ri" (Ifihan ori 22 ẹsẹ 11 de 12)

ẹnyin onkawe mi, mo fẹ ki ẹ ka iwe mi yi dada ki ẹ ma si ṣe ka a kun "Blasfemi" nk tako awọn Woli Ọlọrun bikoṣe awọn Woli eke ti Ọlọrun yio parun laipẹ ọjọ.

ALAPARA SỌRỌ TITI

Nigbati Alapara wọkọ bẹrẹsi tako awọn Woli eke na mo ro lọ an ara mi pe, "họwu kini de to eyi larin awọn Woli wa ati Alapara Ibadan, ṣugbọn emi paapa ti wa lugbadi wọn laipẹ yi nko ni daruko ibẹ.

Enyin onkawe Irohin Imọlẹ, ẹ ṣọra gidigidi o. nitoripe "IKU MBẸ KAARA" bi Yoruba Igbirra, mo sọ mo tun sọ awọn Woli eke ti gbode, aisi iṣẹ ni ilu ti sọ Ọpọlọpọ di Woli eke. Bi mo ti se lugbadi ọkan ninu wọn ni yi o. Bi mo ti nlọ ni arin ọja Agege ni ọkan ninu awọn Woli na pe ni, mo si dahun pe, "alagba se ko si nkan o, O si da mi lohun pe, Oluwa ni o ran on ni iṣẹ si mi, mo bi yin ẹnyin onkawe mi, tani o le gbọ bẹẹ ki o ma duro, ni ba duro, o ni ki nkunlẹ, ni mo ba kunlẹ Ni o ba bẹrẹsi gbadura dapọ ogede pipe.

Ni kukuru ohun ti o sọ pe on ri si mi niwaju Ọlọrun ati enia ni yi.

Oni, "Arakunrin, igbala ti de fun ọ nipa owo, ọmọ ati alafia ara, ṣugbọn a nsọ fun mi ninu ẹmi pe, O ni ohun pupọ o ko le na owo fun awọn ojiṣẹ Ọlọrun rara eyi ni o nkuru asiki rẹ gbiyanju I ti mo a nawo fun ojiṣẹ Oluwa bi temi yi, ki ọna ba la fun ọ.

Werewere ni mo tọwọbọ apo mi ti mo si fun ni sile marun, O si ni ki alafia Oluwa ma ba mi gbe Mo ni Amin.

Ṣugbọn ki o to yi ẹsẹ pada, o juwe sọọs rẹ fun mi pe, ki nwa gba ibukun kikun. Se ẹ mọ pe, emi ọtẹlẹmuyẹ le fin idi koko' mo de ibẹ porongodo.

Ẹo ma gbọ nipa ohuu ti mo ba pade nibẹ ati asiri awọn Woli Eke lẹẹ kẹsẹ. Nigbati mo ba si pari ọrọ ni tan lori awọn Woli eke, ibiti mo ba fi sọ aṣọdun mo fẹ ki ẹ ja mi.

Ẹnyin onkawe mi ki ngto maa bọ o yẹki nfi orin yi da yin lara ya, ẹ ba mi gbee.

Halelu—Halelu ya-a a-a" ẹ Jakuu ẹ ba mi gberin yi,

"Emi ni
Mo tete de
Na mi ni nkan
Ni ibadi
Hallelu ! Halleluya-a-a!!
Emi a rọ mọ
L'ọyan
Iwọ a r'ọmọ
Ni jagunlabi dain

Hallelu ! Halleluya-a-a !!
Ọba mimọ
Wo irun
Ẹlẹmi
Ọga Ogo
Wo irun
Ẹlẹmu mi
Woli ko
Ma jẹ nsun o
Ọba Mimọ
Wo irun
Ẹlẹfun

Eyi ni orin awọn Woli eke o, ki ṣe ti awọn Woli Ọlọrun. nko fẹ ki ẹ si mi gbọ o. Mo fẹ ki ẹ mọ pe, ninu Ijọ a'adura ni emi Ọtẹlẹmuyẹ wa nko si jẹ fi Ọlọrun Ẹlẹda mi ṣe ere rara, ṣugbọn mo fẹ tuna aṣiri wọn ki Ọlọrun ati enia le kodi ago si wọn ni Emi Ọtẹlẹmuyẹ orele o, Oluwa ko mọṣe eyi ni arimọ fun gbogbo wa o.


BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

Ilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orisirisi iwe itufọ tabi ijade Oku

ATI

Iwe gbeyawo

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ERỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985. Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o ri iyatọ*



BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI NWỌN NPE NI - Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọna mọna

**RECHALET**

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di o w o Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi,

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa Egbogi-Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si ni ẹjẹ rẹ mo tonitoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomina pẹlu

Bere Ṣọbu awọn:—
Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)


## Ẹ ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ Ki ẹ si ma Polowo ọja nyin Pẹlu